# IDADURO DE SI AWON OSISE ONINA




SEE YOU PAY THE CORRECT PRICE.



ELETI OFE

A-NJU-WỌN KO SE WI LEJO




AWOGBA Omode fun Girl, Eyi, Hihu-ehin, Orere. Ri Ta Ni Ile Egbogi — ISE — Olodumare Okebola, Ibadan. 116, Great Bridge St LAGOS



VOL. No. VIII 498. ELETI - ỌFẸ LAGOS, SATURDAY, DECEMBER 15, 1956 KOBỌ MEJI (2d.)


## Idaduro de si awon Osise Onina

IJỌRA. Ijọba ta siwa leti wipe iwọn ẹdẹgbẹta enia ni nwọn fẹ da duro nibi iṣẹ ina Lẹntiriki nitoripe ko si owo lọwọ wọn mọ. Oyinbo mẹrinlelogun lowa ninu wọn, awọn Junior Staff jẹ adọjọ lo wa ninu wọn, awọn lebira Oniṣẹ oṣu jẹ ogoji lerugba, awọn olowo ojumọ jẹ ọgọfa.

Ohun ti o fa gbogbo idi ọrọ yi wa ni pe lọdọdun ni awọn oniṣẹ ina Lẹntiriki npadanu gọbọyi ti o fi jẹ wipe ijọba yan awọn igbimọ kan lati wadi rẹ ti nkan yi fi njẹ bẹ lọdọdun. Awọn igbimọ yi lo mu wa ni imọran pe ayafi bi a ba da ogunlọgọ awọn oṣiṣẹ duro ati oyinbo ati enia dudu, bi bẹkọ ile iṣẹ onina, ko ni lọ daradara, eyi si le mu ki a tilẹkun ile iṣẹ na, bi o ba mba bayi lọ

Bi ẹnyin ọkawe wa ba rauti bayi na ni ijọba ṣe idaduro iṣẹ awọn oṣiṣẹ ni wọn ọdun 1930 sẹhin, nigba ijọba Gomina Bourdillon, nṣe ni awọn oṣiṣẹ nkegbe Retrenchment" lasiko na, Oluwa ko fi eyi mọ bẹ.

## Gomina Fi Ase Si Oye Apena

IKẸNNẸ. Gomina Ibadan fi aṣẹ si Oye Apena ilu Ikẹnnẹ ti nwọn jẹ laipẹ yi. Ẹniti nwọn si fi joye nani Oloye Balaja Abubisi Oye na a mori o.

## Commissioner Mbu



Ẹniti a awo ninu aworan yi ni Ọgbẹni Mbu ti o aṣẹ aṣoju ilu Nigeria nilu Ọba lọhun on ni a n wo nigbati o lọ bẹ ile iṣẹ Truscott wo lati se ofin toto awọn aworan ti o ya lasiko ti ọba obinrin fi wa silẹ Nigeria. Ọgbẹni Mbu na lo nyẹ iṣẹ ọkunrun na wo ni.


## THE NATIONAL BANK Of Nigeria Limited

Ile ifi Owo pamọsi yi.
Nfi ọna owo han enia
Bi o ba fẹ jẹ onişowo pataki ao
ran ọ lọwọ nipa wipe ao tọ ọ
si Ọna to dara, ao la oju rẹ
si Ọna owo lati ilu Okere wa
Bakanna si ni a tun nṣe iranlọwọ fun
gbogbo ọja ilẹ wa ti a nta si agbaiye.

ILE IṢẸ WA NI EKO :—
37, Marina, Street, P. O. Box 508, Lagos.

AWỌN AṢOJU WA NILU OYINBO :—
The National Provincial Bank (Overseas Branch)
1, Princess Street, London E. C. 2.

The Comptoir National Descompte, De Paris.
8/13, King Williams Street, London E. C. 4.


## Olepa Mu Cashier Ile Isura Ibadan

IBADAN. Ọga agbowoka ti o wa ni ile iṣura (Treasury) Ibadan ni awọn ọlọpa ramu nitoripe awọn ọlọpa fura wipe o ni lati mọ nipa ina ti o jo ile iṣura ni Ibadan.

Iye awọn ti nwọn fun mu pelu ọga agbowoka ni Ọgbẹni A.O. Adediran, ati L. Winjọbi. Awọn ọlọpa mu moto taxi kan wipe mọto yi 007920 lo gbe ọkunrin kan ati panu epo mọto lọ sibi ile iṣura na Titilayọ Amọo. Apapọ awọn enia ti ọlọpa ramu nipa ọrọ yi jẹ mẹrindinlogun.

Nigbati nwọn bere lọwọ Ọgbẹni S.B.A. Cole wipe njẹ awọn iwe ti o ti jona, nwọnyẹn ha wa ninu awọn iwe ti o nfẹ yẹwo bi ? O si dahun pe, bẹni, ibẹ ni awọn iwe pataki ti mo ni lati yẹwo wa.

Olofintoto ijọba (Auditor) sọ wipe aiyederu pọ ninu awọn iwe ti o wa nilẹ ti ko jona. Awọn akan ti agbọ wipe o jona ni awọn iwe Files, ṣia, tabili Typẹwriter, Kọnbọdu, ap[illegible] iye o-o ohun ti o jona to ẹdẹgbẹtadin-mẹrin. Nwọn si n adi

## Akiyesi

A nfẹ awọn aṣoju ni Abẹokuta, Imọte, Itori, Ijoko, Agbado, Ikorodu, Gbogbo, Aguowa ati Ikosi.
Olotu.

## Obinrin Fi Oyun Odun Meta Bimo

KALABAR. A gbọ irohin wipe obinrin kan loyun lati odun keta ti ko si lagbara lati bi ọmọ.

O wa lọdọ Onisegun ibile kan eleyini bere si toju rẹ ki o to wa fi oyun na bi ọmọkunrin kan ni opin ọdun kẹta.

Gbogbo awọn ẹnin ti o gbọ nipa ti obinrin eloyen ọdun mẹta yi lo amu ẹbun ati dukia bi owo adiẹ asọ ati okan jijẹ lati wa fi ta obinrin na lọrẹ Olorun ko da Ọmọ na si.

## Ijoba Ri Okuta Efun Ni Ifo

IFỌ. Larapa iwadi ti awọn ẹgbe Gbagimọla jade lati mọ wa awọn ohun iyebiye kakiri ni ile Yoruba, ọkan ninu ohun iyebiye ti nwọn ri ni agbegbe Ifọ ni Abeokuta ni efun(lime stone).

Nwọn gbiyanju to ese metadilogbọn le lẹgbẹta ki nwọn to kan okuta na, asi gbọ wipe, awọn okuta ti nwọn ri nibe dara ju ti Ilaro lọ. Nwọn si nsbe okuta na ki nwọn le mọ bi o ti pọ si ati iye ti nwọn na ri.

## Aba Habib Ko Nse Egbe A.G

Ọrọ kan ti o jade ninu iwe irohin wa ti ọsẹ to kọja wipe Malam Habib fi ara mọ ti ẹgbẹ Afẹnifẹre, ọrọ na ko ṣe bẹ,- ki Malam na fori ji wa o.

Oloto

## Oye Owa Ilesha Di Gbanjo

ILESHA. Ọrọ oye Ọba Owa Ilesha ti koro lọwọ awọn ọmọ ọba ati ebi ọba nisisiyi, o ti di onigbanjo ko si wipe ọmọba idile kan nikan lo ni oye na, iye owo giriwọyan ni awọn afọbajẹ nda le oye yi lori.

Ir bia kan wa nisisiyi wipe ọmọba meji pelu abọ £5000 ni awọn da le oye yi lori, ẹnikẹni ti o ba le ri owo yi mu jade ninu ọmọba ni yio joye na.

Ha! ẹnyin ọmọba, ẹ tun oye ṣe o.

## Kayiti Onige Li Ehingbeti

EKO. Meri camọ l'Ereko aja wọ ẹwu, o roṣọ. Eyi li orin ti awọn ara Eko ma akọ laseke kan. Ṣa bọn lode ti oni, oniruuru awọn nkan iyanu li a ari.

Lọjọ Atalata 11th oṣu Dec 1956 ni awọn ara ilu Eko tun ri Igo nla ti ọti Star Lager kan ti o nfo bi, ẹiyẹ lefurufu.

Eyi ara, Igo ọti Bia nfo loju ọrun, o mu wa ranti orin kan ti awọn akọ nilu Eko bayi pe, Mo ri kini kan to nfo leferefe, Oriṣiriṣi ohun ara li a nri nilu Eko. Igo tun nfo? evi ara.

## Alufa Eni Owo Kuye Fe Fise Sile

A gbọ ihin wipe Alufa Ẹsi ọwọ W.E.B. Kuyẹ, ẹniti o ti gba oye ali M.A, ti o si ti jiṣẹ Ọlọrun nilẹ Yoruba ati loke Ọya, nfẹ fi iṣẹ na silẹ, lati gba isimi lẹhin adọta ọdun ti o ti mbe lẹnu iṣẹ na.

Alufa Ẹsi ọwọ yi, ṣegẹbi ti ẹgbọn rẹ ti a npe ni J.G. Kuyẹ lo ara ati igbesi aiye wọn fun ilọsiwaju ati igbega ilẹ Yoruba. Iwe ti Principal J.G. Kuyẹ ṣe la jẹki ọpẹ awọn ọmọ Yoruba le mọ iwe Yoruba ni kika.

A gbọ wipe awọn igbimọ Diocesan ti jẹ ọhẹn si ibere Alufa na lati simi nitoripe tirẹ to bẹ. A gbọ pe yio berẹ isimi rẹ na ni opin ọdun ti a wa yi.

## Awon Onilu ile Ijesha sopanpa

ILESHA. A gbọ irohin wipe awọn awujọ, ẹgbẹ Onilu to mbẹ nilẹ Ijẹsha sopanpa wipe, awọn ko ni sọ konkoṣe de ipo ti awọn yio lulu, ohun kohun ti o wu ki o de iba ṣe wipe nwọn fẹ jọba, awọn ko ni lu ilu.

(Wo Yoku Loju Ewe Keje)


## EHIN DIDUN PELU IRORA



Ọna bibọ lọwọ irora?

Njẹ iwọ mọ pe ẹkan ninu ohun ti o fa sababi ẹhin didun ni Kidinrin?

Bi ehonkohun ko ba ṣe Kidirin wa nwọn a ṣe gbogbo eri kuro ninu ẹjẹ ki gbogbo ẹya ara wa le ma siṣẹ dede nigbati Kidinrin wa ba nṣe tikọtikẹ, ti ko si ṣiṣẹ dede, gbogbo eri a wọjọ sinu ẹjẹ a si ma a mu ki ẹhin dun ni.

Egbogi onirodorodo fun gbigbemi ti Ọgbẹni De Witt ṣe jẹ egbogi atata ati atamatase ti o nmu ki ẹhin didun salọ kiakia nipa titun ẹjẹ ṣe ati nipa mimu irora ati alafia ba ẹnikẹni ti ẹhin didun na mba ja.

O san ki ẹniti ẹhin didun mba ja tete fi egbogi ti a nsọrọ rẹ yi ko leja fun ati ba le jẹ igbadun aiye jupẹ ki a fi dagunla ki o si ma di ẹnibẹ lọwọ lẹnu iṣẹ rẹ ati ni igbesi aiye rẹ.

Egbogi De Witt jẹ egbogi ti a ri nlo lati aiyebaye wa, titi o fi di oni yi ko mba wiwo ẹhin didun san si, egbagbeja ọna ti o ti lo De Witt lo nkan sara si fun jijẹ bi idan rẹ. Nitori idi eyi, ogunlọgọ iwe ni awọn kọ ṣọwọ siwa lati fi dupẹ fun ore ribiribi ti De Witt uṣe fun wọn. Lẹ sile tita egbogi ki o lọ ra tirẹ loni fun lilo nitori ijafa lewu

A se De Witt's Pills ni pataki fun Wiwo ẹhin didun, irora orikerike latanlatan, ibadi sisan.

A fọwọ sọya pe De Witt's jẹ ojulowo egbogi, gbogbo ohun elo ti a si fi se lo pe perepere ti awọn alaṣẹ ilera si kan sara a pe ko si kolofin kankan ninu rẹ



DE WITT'S PILLS
for Kidney and Bladder Troubles



## Ebun Odun Titun Wa Je Orire

Ninu Idije £275.000/ Ti Sangam

Ẹniti o ba yege ninu gbogbo rẹ yio jẹ 255,000/-
Ẹniti ile kini ati ekeji tirẹ ba dọgba mọ tiwa yio jẹ 20,000/-

| | | | |
|---|---|---|---|
| | | | |
| | | | |
| | | | |
| | | | |

Ṣe eto lati nọmba 6 si nomba 21 ninu oju kọkan, tobẹ lati oke si isalẹ, lati ọtun si osi, lati igun kini si ekeji ki ọkọkan rẹ jẹ 54 ni iṣiro pọ. Ẹkanṣoṣo ni a fẹ ki o lo number kan.

Bi o ba di ni 20th oṣu Jan 1957, a ko ni gba ẹnikẹni laye mọ. Ọkọ ofurufu ni ki ẹ fi gbe.

Esi rẹ yio jade ni 31st oṣu Jan 1957, 14/- fun ẹyọ kan 30/- fun mẹrin, 70/- mẹrindilogun, 90/- fun merinlelogun 120/- fun mejilelogbọn ati bẹ lọ. Ẹniti o ba fẹ, le kọ sinu iwe, miran ko fi ranṣẹ. Ẹnikẹni ti o ba fẹ ki o fi Postal Order tabi Money order ranṣẹ, Nọmba ti Gẹsi le fẹ ki ẹ lo. Ẹniti tirẹ ba dọgba pọ pelu tiwa lo ṣe daradara. Ede Gẹsi ni ki ẹ fi kowe si wa.

Ẹniti o ba fẹ ẹda esi, ki o fi 1/- ranṣẹ Eyiti a ba ṣe abẹ ge,

| Last Result Total 50. | | | |
|---|---|---|---|
| 13 | 6 | 20 | 11 |
| 12 | 19 | 5 | 14 |
| 9 | 18 | 8 | 15 |
| 16 | 7 | 17 | 10 |

Fi ranṣẹ si Sangam Office
P. O. No. 13 ALIGARH
[INDIA]

## Kini Odun Keresi-mesi Ti Da Yi

Gbogbe ẹayin ọkawe wa ẹ ba mi dupẹ lọwọ Ọlọrun fun aanu rẹ ati ore rẹ si wa lati ọdun 1947 titi di oni ti a ko fi ri daa! Ha! ogo ni fun Ọlọrun.

Laju tiwa o fẹrẹ dabi enipe ọdun ti a nṣe nigba atijọ fẹrẹ ladun ju ti isisiyi lọ. Nitoripe nigbani, bi ọdun keresi-mesi ba mbọ bayi, gbogbo awọn ọmọde kekeke yio ma fi ifun ọpa ko ile Ṣẹsi, ati lantan (lantarn) lati magbe yide kiri lọjọ aisun Keresimasi.

Awọn ẹlomiran, yio ma mura Kereta, omiran lati gbe Boyi Egungun Aguda jade, omiran lati gbe Epe awọn ijọ Anglikan.

Eyi nikan kọ, tọsan toru ni awọn arasọ yio ma ran ti Kareta ati ti awọn Kao bọyi (Cow Boy) Gbogbo iru iwọnyi lo nmu ọdun awọn Onigbagbọ dun.

Ṣugbọn lo de ti oni, ko tun si irufẹ rẹ mọ. Bi o ba tilẹ ri awọn Igbagbọ ti o fẹ yọ si, bi nwọn ba ti ri o lokere ni iwọ yio ma gbọ bayi pe:- Riwo.-riwe, yago fẹṣu, tani jẹ duro. Ha! Igbagbọ.

## Obinrin Eleja Kan Padanu

YABA. O ti jẹ aṣa fun awọn obinrin to nṣeja wipe, bi o ba ti gbe ẹja yala gbigbẹ tabi tutu lati Makoko, ko si ẹuiti ele pe wọn ti nwọn o da oluwa rẹ lohun.

Obinrin kan lọ ra ẹja yiyan Salmọn ni Makoko, o ngbe lọ si Sabo lati lọ ta a. Gbogbo enia to ri ẹja yi lo nfẹ ra a, nwọn bẹrẹ si pe ẹlẹja na, ṣugbọn ko dahun gẹgẹbi iṣe wọn.

Koiti rin jina nigbati Basikulu kọlu ẹlẹja na, gbo gbo ẹja naiosi sojude inu ẹrọfọ Pọtọ-pọtọ. Kosi ibiti enia le gba de ibẹ nitori ira amujẹjẹ ni

Tohun tẹnu na ni obinrin miran tun gbe ẹja yọ, eyiti opọju ti obinrin akọkọ lọ, gbogbo ọja tirẹ lota tan ki o to de ibiti obinrin na ṣubu si ẹo ri, aṣeni ti o nṣe ara rẹ.

## E Ma Ka Iwe Irohin Ileti-Ife Ki E Si Ma Polowo Oja Yin Sinu Iwe Irohin Aladun Yi.



# ELETI QFE

A-NJU-WỌN KO SE WI L'EJQ
EDITORIAL OFFICE & WORKS CABLES & TELEGRAM
28, Kosoko Street, Lagos "ELETI - QFE LAGOS"
P. O. Box 467 Phone 23370
VOL. VIII. NO. 49?, LAGOS, SATURDAY DEC, 15, 1956.


## E kabọ o, eyin omo Abile soro

Ko si orin ti a le kọ si ilu gbedu, ayafi ero ya wa wo; nitori idi eyi, ni a ti ṣe mu orin kekere ti o wa loke iwe ọsẹ yi wa lati fi ki awọn ọmọ wa ti nwọn lọ silu Melbourne nilẹ Australia ku abọ irin ajo wọn na. Gbogbo awọn ọmọ wa ni a ki lọkan-kan, a si tun ki Olotu wọn Oloye L. K. Randle ku irin ọna. Nwọn ku ifẹ ilu, nwọn si ku ifarada.

Ko nṣe ohun kekere, ki bale ile fi ile rẹ silẹ pẹlu gbogbo awọn ebi rẹ, lati lọ silu ajilara ailẹbi ati ilu ti akoni iyekan.

Awọn enia awọnyi lọ silu Australia lati gbe ilu Nigeria, ga, nwọn sa ipa wọn, a si gbọ okiki ilẹ enia dudu kakiri agbaiye. Eyiyi na lo nifi wa ohun ribi-ribi ni awọn ọmọ wa yi ṣe fun ile Nigeria.

Bi nwọn ti ngbe orukọ ilu wa ga yi, ki Ọlọrun ṣe agbega rere fun wọn lọkọkan. Ẹ kabọ o, ẹnyin ọmọ Abilẹ sọro kilẹ lanu kabọ o.

## Oloye Okorodudu



Eniti a nwo yi Oloye Okorodudu, ti o nse asoju fun Ijoba Iwo--orun nilu Oyinbo on lo gba isinmi wa sile lehin odun keji ti o ti lo se atipo nilu oyinbo 0gbeni Awosika lo gba ipo re de lohun.

## Ofo Se Oba Gesi



LONDON. Ọfọ kan ṣe ọba Gẹsi, ninu eyiti iku pa Anti rẹ agba kan ti a npe ni Ọmọba Maria, Louis nigbati o dagba di ẹni ọdun mẹrinlelogorin.

Oloye yi jẹ ọmọ-ọmọ ọba Obinrin Viktoria aisau kekere kan lo de si i ki iku to pa a yi.

A bi i lọlọ kejila oṣu August 1872, anti agba lo jẹ fun oba ti o wa nisisiyi, o si jẹ ẹgbọn ọba Joji karun. Orukọ iya ati baba rẹ ni awọn ọmọba Kristiani.

## Amerika ko mo tele nipa ogun to ja Egypt

PARIS. Aṣiwaju awọn Oṣelu ilẹ Faranse lo sọ wipe, nigbati Gẹsi ati Faranse fi lọ ja Egypt logun nṣe ni awọn ṣe e ni aṣiri larin awọn mejeji laijẹki Amẹrika mọ ohun kan nipa rẹ, nitoripe bi nwọn ba mọ' nwọn ko ni jẹki awọn gunlẹ silẹ Egypt.

Ohun ti o si jẹki awọn ṣe bẹ ni wipe, bi a ba jẹki Amẹrika mọ, ko nigba fun wa lati ṣe bẹ, a wa na pẹlu ko ni gba si Amẹrika lẹsu, nipa bẹ edekoyede yio de o si le ṣe bẹ ki o di ogun nla larin wa.

Bi ẹ ba ranti, ni ọdun 1939, nigbati Hitler gbe ogun silu Ṣẹko-slo-fakia, Faranse ati Gẹsi fẹ ṣigun si awọn Jamani nigbana, awọn ẹgbẹ Majẹobajẹ ro wipe alabosi ni wa. Iba ṣe wipe nwọn fi wa silẹ lọjọ na ni ki awa mejeji kolu Hitler, ogun to di nla na iba ti ri bẹ rara, ogunlọgọ awọn to ba ogun na lọ iba ṣi wa laye titi di oni.

Nassar jẹ Hitler kekere, awa Faranṣe ko ni gba ki ete ati ero Nassar ma ṣẹ, ko maṣe tun wa dabi ti Hitler nijoun. Awọn Rọṣia le fẹ lati gbeja, nitoripe nwọn bori ni ilu Hungary, ṣugbọn awọn ara ilu na ko fi Rọṣia lọrun silẹ.

Iru ọna ti ẹgbẹ Majẹobajẹ ngba lati fi pari ija mu ki ẹru ba Faranse. Bi Majẹobajẹ ba paṣẹ nwọn ko ngba aṣẹ rẹ gbọ, ṣugbọn a ko fẹ ki nwọn gbọ wipe Faranse lo kọkọ yọ ara rẹ kuro ninu ẹgbẹ Majẹobajẹ,

## Okunrin Ni Alhaji Maito

ILORIN. Ọrọ kan ṣele ni Ilọrin ninu eyiti a gbọ wipe Alhaji sọ pe Yoruba lo ni ilu Ilọrin, nṣe ni awọn Filani wa kọ wọn ni kewu. Nisisiyi a ti ke ọta, a si ti gbe ọta mi, a si tun ta giegie pelu, nitorina ki awọn Filani ma lọ silu wọn

Ọrọ yi ni ọba Ilọrin gbọ, ti o si ranṣẹ pe Alhaji Maito ati gbogbo ilu jẹ si arin ọja ọba. Nigbati oju pe, ti ẹṣẹ pe tan Oyinbo Ajẹlẹ wa nibẹ oyinbo Ọlọpa wa nibẹ, ẹṣẹ gbogbo awọn oṣelu lo pe sibẹ.

Ọba wa sọ fun gbogbo enia wipe Gbogbo ẹnyin Jọama mo ki yin o. ọ ba mi bere lọwọ Alhaji Maito kini awa Filani ṣe ti o fi sọ wipe ki a ma lọ silu wa?

Nigbati Alhaji Maito dide, ariwo Nọsara gba gbogbo ọja ọba kan. Bi awọn Talaka Parapọ ba wipe Nọsara awọn ọmọ ẹgbẹ N.P.C. yio dahun wipe Salaa salaa

Alhaji dahun wipe, awa oṣelu meji lo mba ara wa tayo, a ko fi ba ọba wi rara lotitọ ni mo sọ wipe Yoruba lo ni Ilọrin Balogun Afọnja lo si kọkọ tẹ ilu Ilọrin yi do, Kewu ni awọn Filani wa kọwa, asi ti sọki, ati kewu ja.

Ọba Ilọrin tun sọ pe, on ko fi ṣe tija rara, ṣugbọn idi rẹ ti on fi pe ipade yi ni wipe, nitori ki ọtẹ le tan nilu Ilọrin li on ṣe ṣebẹ.

Alhaji Maito dahun pe, bi o ba jẹ wipe lododo ni ọba nwa alafia si ilu, o yẹ ki ọba ṣe ikilọ fun awọn Aṣọgbo. awọn olota ijọba ibilẹ, awọn Dawodu, awọn Wolewole, ati awọn Olota ijọba, ki nwọn ye fi iya jẹ awọn ọmọlẹhin mi, nitori ọrọ ilu.

A tilẹ gbọ wipe oba na sọ wipe ẹnikẹni ko gbọdọ sọrọ sinu iwe irohin laiko fi ba on sọ.

Nigbana ni Alhaji Maito wa bere lọwọ ọba wipe' iwọ ha ṣe tan lati dapọ mọ awọn Yoruba? Ariwo ta ge-e wipe, Bọni, ao dapọ mọ Yoruba ibosi Awo! Awo! Awo! ni awọn fi tuka, Ko si ija, [illegible] ko si ita,

# LAGOS RACE CLUB
## CHRISTMAS MEETING

**SATURDAY 22nd, WEDNESDAY 26th, SATURDAY 29th DECEMBER, 1956, TUESDAY 1st AND SATURDAY 5th JANUARY, 1957.**

### FIRST DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 1 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.00 p.m. |
| RACE No. 2 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3.35 p.m. |
| RACE No. 3 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4.10 p.m. |
| RACE No. 4 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 4.45 p.m. |
| RACE No. 5 | Eight Furlongs Handicap Middle Division | 5.20 p.m. |
| RACE No. 6 | Seven Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 7 | Seven Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |

### SECOND DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 8 | Nine Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 9 | Six Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 10 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 11 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 12 | Six Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 13 | Five Furlongs Handicap Top Division | 5. 55. p.m' |
| RACE No. 14 | Five Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p,m. |

### THIRD DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 15 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 16 | Eight Furlongs Handicap Bottom Division | 3. [illegible] p.m. |
| RACE No. 17 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 18 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 19 | Nine Furlongs Handicap Middle Division | [illegible] p.m. |
| RACE No. 20 | Six Furlongs Handicap Top Division | 5. 55 p.m. |
| RACE No. 21 | Six Furlongs Handicap Top Division | 6. 30 p.m. |

### FOURTH DAY

| | | START |
|---|---|---|
| RACE No. 22 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No. 23 | Five Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 35 p.m. |
| RACE No. 24 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m. |
| RACE No. 25 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 4. 45 p.m. |
| RACE No. 26 | Seven Furlongs Handicap Middle Division | 5. 20 p.m. |
| RACE No. 27 | Polo Scurry | 5.55 p.m. |
| RACE No. 28 | Eight Furlongs Handicap Top Division | 6.30 p.m. |

### FIFTH DAY

| | | |
|---|---|---|
| RACE No. 29 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3. 00 p.m. |
| RACE No, 30 | Four Furlongs Handicap Bottom Division | 3, 35 p.m, |
| RACE No, 31 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4. 10 p.m, |
| RACE No, 32 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 4, 45 p.m, |
| RACE No, 33 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5, 20 p.m, |
| RACE No, 34 | Five Furlongs Handicap Middle Division | 5, 55 p.m, |
| RACE No, 35 | THE GOVERNOR GENERAL'S CUP Ten Furlongs - Top Division | 6, 30 p.m, |

## Okunrin kan sin ara re

ITALY. Nilu kan li [illegible] gbe ilẹ Italy, Okunrin olowo kan ṣalaisi [illegible] dinleje awọn enia lo si tẹle oku olowo na lọ si itẹ oku.

Nigbati nwọn de ile oku ohun abami kan ṣele. Ohun na ti o ṣele niyi wipe; nigbati nwọn gbe oku [illegible] ibi koto ti nwọn [illegible] lowo [illegible] koto okun [illegible] ọrọ re [illegible]

[illegible] oku olowo [illegible] ti nwọn si bere si [illegible] miran ni gbigbe.

# Ariyo Ko Omo Jade Ni Kano

KANO. Ọgbẹni Z. M. Adyọ ti o nṣiṣẹ ninu Ketu Ijọba ibile, lo se ikomọjade ọmọ ti Ọlọrun fi ta a lọrẹ. Nṣe ni ọṣẹ awọn ọmọ ẹgbẹ Ansar-deen pọ tiba. Alhaji Abdul Lasisi lo ka watabs le ọmọ na lori o si fun ni oruko yi Sikirulai Alade.

Lẹhin eyi ni ijo wa sọle. Diẹ ninu awọn gbajumọ to wa sibi ikomọjade na ni awọn nwọnyi:- Ọgbẹni A. K. Adarohuumu, Baṣira Olukọtun, Alhaji Lasaki, Tairu Ọnasanya, Ọ. Ikiọla, A. O. Oseni, Y. A. S. Akinyọde, M. K. Idris, Giwa, Ajala, Ogabi, Salisu, Erogbogbo, Onabanjọ. Ẹsọ ko gbeji nile baba tafalu.

# Apa Enia Mo Ohun Ti O Nse

Lati Ọwọ Ẹsọ

Nigba aiye ọba Ṣodẹkẹ ni Abẹọkuta, ọkunrin Imaro kan wa ti o nṣe owo, ama ba awọn Alajapa lọ si Eko ati Agbadarigi bi o ba pada de yio mu aṣọ aran Taiwo, aran Oleyin, yio fi ta ọba lọrẹ, nigbamiran yio ra aṣọ Damasi ati awọn nkan mere-mere lati fi ta ọba lọrẹ.

Si ọkunrin yi ti nta ọba lọrẹ, bẹni ọba ngba a, alalikun ọba ko mọ ri. Nigbati ọrọ tita yi npọju, Ọba bere wipe tani ọkunrin na ti o nfi awọn nkan daradara awọnyi ranṣẹ simi? Awọn ẹru ọba dahun pe Imaro ni ọkunrin na. Ọba tun bere wipe kilo nfẹ lọdọ mi? Nwọn si tun dahun pe, o nfẹ joye ni Ọba si dakẹ.

Gbogbo awọn Aguda ati awọn Imaro ti o mọ nipa ohun ti ọkunrin na nṣe lọ fun ọba lombu ni eebu wipe, Ha! Apa, amumimurawe, ẹja afewe pa. lati ọjọ ti o ti nta ọba na lọrẹ yi, kini ohun ti o fun ọ, tabi ọba na ha tilẹ mọ ọ ri? Apa. Ọkunrin Imaro na, a ma dawọn lohun bayi wipe, ẹ fi mi silẹ, ẹ ranṣẹ ba ohun ti mo nṣe jẹ. Nitoripe apa enia mọ ohun ti o nfi owo ṣe. Sibẹsibẹ ko ye ta ọba lọrẹ.

Lọjọ kan ọba Ṣodẹkẹ ranṣẹ si Imaro na ki o wa fi oju kan an ni Afin. Nigbati ọkunrin na de Afin, ọba bere wipe, kini iwọ nfẹ ki emi ki o ṣe fun ọ, ti o fi nta mi lọrẹ nkan olowo iyebiye bayi? ọkunrin Imaro na dahun pe, Kabiyesi, ki ọba pẹ, ki ade pẹ lori ki bata pẹ lẹsẹ Alaiyeluwa. Iba ohun ti mo nfẹ ni wipe nibikibi ti ọba ba gbe joko si, bi on ba ti yọ lokere ni ki ọba ti paṣẹ pe ki nwọn fi ona silẹ fun on, ati wipe bi on ba ti fi ẹnu ko ọba leti oh nkohun ti ohun ba wi, aṣe ni ki ọba rerin, ohunkohun ti on ba si ṣe niwaju ọba, nṣe ni ki o jẹgun. Inu ọba si dun si ibere na, o si gba fun u.

Ọjọ kan pe, ti ọba nfẹ ṣe ajọdun Molẹ kan oju gbogbo ara ilu pe, ati ijoye, ọba papan gunwa, bẹni ọkunrin Imaro yi yọ lokere, o ola arin awọn enia ati ijoye bọ, nigbati o de ọdọ ọba o fi eti ko o leti, ọba si ka si ẹrin ọkunrin Imaro na si kuro nibẹ o lọ.

Lẹjọ kan awọn gbajumọ meji kan daran, tobẹ ti ọba ni lati pa awọn meji na, awọn bẹ ọba ni abeti Gbogbo ijoye lo a ro yi ti. Nigbati o di alẹ ọjọ ku ọla ti ọba yio pa awọn meji awọn ranti ọkunrin Imaro yi.

Nwọn lọ ka, awọn si bẹ ki o ba wọn bẹ ọba, ọjọ pe, agbo ti, enia da bi omi, eni ti yio pa awọn enia na ti bọ si agbo, bẹni Imaro yi yọ ti o si ala-rin gbogbo enia bọ, o fi eti ko ọba leti, ọba si ku si ẹrin, nigbati o pada de agbo, o fi ọwọ kọ awọn ọdaran meji ji, o si ko wọn lọ nṣe ni ọba nrẹrin. Nitorina apa enia mọ ohun ti o nfi owo rẹ ṣe.

# Igbesi Aiye Daddy J.H. Doherty

Ologbe Daddy J. H. Doherty jẹ ọsinnare enia, ti o si nfi tirẹ gbe ti ẹni ẹlẹni. Bi ologbe yi ba nṣe ore rẹ, ko ni bojuwo ehin wo lati bere ohun kan pada. On ni ẹniti o lowo julọ nigba aiye tirẹ, ti ko si ẹlẹgbẹ rẹ, ko nṣe ẹniti yio ṣe ore tan ti yio si tun loṣo ti i. Ṣugbọn o fẹran ẹniti o ba mọ ore pupọ. On ni nwọn npe ni olowo ilẹ Nigeria nigba tirẹ.

Abi ologbe yi nilu Ijero lọjọ 16th oṣu August 1866 oruko iya rẹ ni Ariwoọla, baba rẹ si jẹ Katikisti fun ijọ C.M.S. nilẹ Ekiti. O kọwe nile iwe C.M.S. Training Institute ni Eko Nigbati o kuro nilewe, o ṣe akọwe elekuro lọdọ ologbe Sedu Olowu ni ọdun 1888. Laipẹ o jẹ oye ọga nibẹ.

O fi iṣẹ Olowu silẹ o si bẹrẹ iṣẹ tirẹ ni ọdun 1891. O fi pọun mẹtadiladọta bere owo tirẹ were were, were bayi lo se ti owo re di egbaji ni Bank O wa lọ ra ile lẹdẹ ijọba ni kọbọ kan fun ẹsọ kan. nitoripe ibẹ jẹ ira. Nigbati o kan tan lo wa kọ ile ti Alakoro sibẹ ni ọdun 1898 o si ko aṣọ aran Ṣẹda Damasi Siliki, Ayẹ ati itẹkọ kun inu rẹ. O ti ṣi ṣọbu ọti fun tita ri ṣugbọn ni ọdun 1896 lo fi ọti tita silẹ.

Ologbe yi bimọ pupọ, o nile pupọ, o si nile pelu. Ọkan ninu awọn ọmọ re ni Onisẹwo Bayọ Doherty ti o nṣe ọkan ninu awọn gbajumọ ilu Eko yi.

Koiti pari.

# Olopa woya ija pelu awon olosa

IBADAN. Awọn ọlọṣa nwọnyi, Thomas ẹgbe, Richardson Ṣineke, Jenifẹs Sineke ati Chiles Anene, awọn mererin nwọn lọ ji moto kekere kan ti nwọn fi aṣiṣe ni ile iṣẹ Prime Minister, awọn lọ si ọja egbeda ni bi ti nwọn nra koke, nwọn gbe apo keko meta pelu abọ ni ajia oru awọn fo ṣọbu Were awọn ọlọpa wa ka wọn mọbe.

Gere ti awọn foju kan ọlọpa, awọn mererin ko sinu moto, awọn salọ. Awọn ọlọpa gba tele wọn lehin, Eyiti a npe ni Ogbe fi ori fọ jigin iwaju, ni awọn meta yoku ba ba fa ọbe yọ nwọn si ba ọlọpa woya ija. Ọlọpa ṣe wọn leṣe pupọ nwọn si gba ọbe na kure lọwọ wọn, nwọn si ko wọn lọ si Adeọyọ fun itọju.


## Kere o!

A ti ni orişirişi ogun Germany to ṣeṣẹ de, fun oniruru aisan tọkunrin tobinrin. Tete wa ra tirẹ k'o to tan.

**J. A. AJAO BROTHERS**

MEDICINE STORES

7, Egerton Road, Lagos



## IMORAN FUN ENYIN ABIYAMO

Enyin abiyamọ ẹ wa ra ỌMORELA o dara pupọ fun awọn ọmọde.

Ama je ki emode ri orun sun daradara o dara fun otutu, ikọ ati orisirisi arun miran ti o nsa mba omode ja ni asiko ehin. Opolopo abiyamo le ti le egbogi yi fun omo wan ti wan si so wipe edara pupo fun awon omode

ỌMỌRELA BABY MIXTURE

(SILE MEJI ABO 1/6d. FUN IGO KAN)

O wa lọdọ:—

COMMERCIAL MEDICINE STORES

(Qualified Chemist)

10 VICTORIA STREET, LAGOS



Awọn gende ọkunrin ti o duro ti a nwo nwọnyi ni awọn Dankare ọmọ ilẹ Nigeria, ti nwọn fi ori li okun la ọsa lọ si ilu Melbourne ni ilẹ Australia lati fi orukọ ilẹ wa han araiye

Ko nṣe igbati enia ba lọ si ogun ti o de ogun ti o si pa mejo ni a npe ni jagun-jagun, ṣugbọn oruko ni a nfẹ la, bayi wipe ilẹ Nigeria wa ninu awọn ti o ṣere na, ati wipe, awọn ṣe iwọn iba ti nwọn le ṣe.

Ẹnyin Olympian ẹ kabọ o, ẹ ku iriṣ, a ti mọ riri iṣẹ ti ẹ ṣe, bi ako baiti ku, lọjọ kan ni ao jẹ ẹran ti o tobi to erin. Ṣugbọn ẹ maṣe ju awa silẹ bi koṣe ki ẹ mura siwaju.

# Ode Kan Wo Ewon Ojo Kan

ỌYỌ. Agbọ irohin wipe ọkunrin ọdẹ kan ṣeṣi pa ẹni kan ninu igbo. Bi ọrọ na ti lọ niyi wipe, ọdẹ wa ninu igbo, nigbati o ngbọ wuru-wuru ni inu igbo kan, a si gbọ wipe igbo na di bara-bara tobẹ ti enia ko le riran ri ohun to mbẹ ninu rẹ.

Ọdẹ yi yinbọn si arin igbo na, o si pa ẹni kan ninu igbo na laimọ. Adajọ ro ọrọ na siwa sẹhin, o ri wipe ọdẹ na jẹbi iṣeṣi pa enia, Adajọ ni ki na o sare lọ si ẹwọn ọjọ kan ṣoṣo pere a si gbọ pe ki ilẹ to ṣu, o ti jade ni ẹwọn.

# Itan Si Aje Obinrin

Ṣ. obinrin aje na ti ri i ninu jinin rẹ wipe ọkunrin kan nlepa rẹ bọ pẹlu ogunlọgọ enia, o si pe ẹfọ, ẹfufu lile si de o saja ọkọ awọn ọta rẹ da, ṣugbọn o gba ọkunrin eleri wọn la. Ki o ba le fi ṣe ọkọ.

Nigbati ọkunrin na gunle sori apata kan, si ran alijannu kan lọ fi ọkọ tuu wa sile Enia mejọ ninu awọn ti ọkọ wọn sojude we titi nwọn si gunle sori ile. Eni tere, ejitere ni nwọn nrira wọn he.

# Eniti O Pa Enia Ni Lati Ku

BAMENDA. Ọkunrin kan ti a npe ni Njombu ti o nṣe agbẹ iṣu koko ni a gbọ wipe o fi ọbẹ alasoro gun aburo rẹ kan pa ti orukọ rẹ njẹ John Bẹkinwe

Nigbati ọrọ na dewaju Adajọ ninu kotu Asizi nwọn sọ pe ọkunrin apania na ko mọ igbati o siṣe baruku yi nitoripe o ti muti yo nigbana.

Adajọ na dahun wipe on ko gbagbọ wipe ọti ti o mu yi le jẹ ki o pa enia mọ ṣebi ọti ni o mu ọti na le ba yọ ọbẹ la lọwọ lati fi paniа. Nitorina ṣaiṣi o ba paniа ni a ni lati ma ida kọja ori rẹ. Ki awọn lọ yọ igi fun Njombu.

# Awon Onilu Ijesha Sopanpa

o bere leju ewe keji

Ohun ti a gbọ wipe o fa sababi yi ni wipe awọn igbimọ sọ wipe ki awọn Onilu bere si ma gba iwe ki nwọn to ma lu lu.

Ṣugbọn awọn Onilu sọ wipe Alagbe ni awọn, ko si si ohun ti awọn fi yatọ si Onibara, bi nwọn ko ba pọn enia ni aṣọnbo, awọn ko ni jẹun. Ni wọn igbati awọn Alumọngeri tabi awọn Alufa ko ba n nsanwo ki nwọn to siṣẹ wọn, awọn na ko ni sanwo.



Published by the
FEDERAL INFORMATION
SERVICE, LAGOS

The Ideal Christmas Gift
THIS PICTORIAL SOUVENIR OF THE
Royal Tour Of Nigeria

containing a representative selection of photographs including man[illegible] in colour, of some of the memorable events of the Visit of Her Majesty the Queen to Nigeria. This official record recaptures the warmth and enthusiasm with which we in Nigeria greeted the Queen who walked among us.

From booksellers and agents throughout Nigeria.

PRICE 2/-

Wholesale enquiries to N.P.P. Co., 172 Broad St., Lagos




ARADAN NERVIGORA

Ogun ẹjẹ pataki fun imarale agba ati arẹmọ pipe fun awọn alaya pupọ. O dara fun inarun, ẹjẹ didu, iṣokun oju, gbigbọn ọwọ, ailesun, ailokun ninu, ati irufẹ arun bawonni. O jẹ ajidewe fun awọn ti agbara wọn ndinku. On na gan ni ọkunrin yi lo ti o fi di "Afẹṣẹ kun bi ojo." 5/6d. pere pẹlu owo ọkọ 1/6d e.e. 7/- Post Free.

**The Egba Trading Aradan Stores** 112, Denton Street, 18, Denton Bridge Street, P. O. Box 2. Ebute - Metta. Phone 44153. A tun wa ni New Motor Park (Ogunpa) Ibadan.

# Ebo bo Ilorin Lo Nfe Le Sile Yoruba

ILORIN. Irohin Kan wa lati ilẹ Ilọrin wipe awọn N.P.C. sọ wipe gbogbo awọn Ilọrin lo fi ara mọ ilẹ Hausa.

Malam Ketengere ti o nṣe akowe ẹgbẹ Afẹnifẹre sọ pe gbogbo awọn ara Ilọrin lo nfẹ faramọ ilẹ Yoruba. Nitori ibẹ ni nwọn nlo si, awọn si gbọ ede ara wọn Ara ilẹ Ilọrin melo lo mbẹ ni Kano tabi ni Ṣokoto.

Ilọrin ko nṣọ ede Hausa papan. Saki ọba Ilọrin ti o jẹ Filani, boya lo gbọ ede Hausa tobẹ, ijọkan lọgbọn lo nsọ ede Hausa ṣugbọn ojojumọ lo nsọ ede Yoruba.

Nitorina, Yoruba ni Ilọrin a si nlọ silẹ Yoruba Nọsara! Awo! Nọsara! Awo!

# Oloye Anthony Enahoro



Eiti a nwo yi ni Oloye Toni Enahoro on ni eniti ijọba Iwọ-Orun ran lọ si ipade awọn jagun-jagun nilu Accra. Ipade na bere nilu Accra lọjọ Monday 17th oṣu Dec, 1956 Ọrọ pataki ti awọn fẹ so jẹ larin awọn jagun-jagun apa Iwọ-Orun ile Afrika Oloye Enahoro ko ni wọkọ ofurufu ọna ilẹ ni ylo gba de ọhun,

187

# VACANCY

Applications are invited for the undermentioned posts in the Geological Survey Department.

1. Geological Assistants, Grade III - Particulars in Government Notice No, 2215 in the Federation of Nigeria Gazette of the 6th of December, 1956.
2. Survey Draughtsmen Grade III - Particulars in Government Notice No,. 2214 in the Federation of Nigeria Gazette of the 6th of December, 1956
3. Museum Technical Assistant - Particulars in Government Notice No, 2216 in the Federation of Nigeria Gazette of the 6th of December, 1956.
4. Second and Third Class Clerks - Particulars in Government Notice No, 2217 in the Federation of Nigeria Gazette of the 6th of December, 1956,

188

# Meteorological Service Vacancy for Meteorological Observer Grade II

Applications are invited for appointments as Meteorological Observers Grade II in the Meteorological Department of the Federation of Nigeria.

Qualifications :--

(a) The West African School Certificate with four credits, including English Language; or
(b) The General Certificate of Education with four passes at ordinary or advanced level, including English Language or
(c) The Cambridge Oversea School Certficate with four credits, including English Language; or
(d) The London Matriculation Certificate; or
(e) The Junior Civil Service Entrance Examination.

2. After an initial period of 6 - 9 months training in the Lagos area at a salary of £150 per year recruits are posted for duty outside Lagos at a salary of £195 with annual increaments of £9 thereafter to £276.
3. There are good opportunities for promotion to the higher posts of Meteorological Observer Grade I [£288 - £378], Meteorological Assistant Grade II [£405 - £558] and Meteorological Assistant Grade I [594 - £744]. Observers and Assistants of exceptional promise are selected for study leave, in Nigeria and the United Kingdom, for further academic and technical training to enable them to qualify for posts in the Meteorological Officer [£600 - £1380] and Meteorologist [624-1380] grades,
4. Application should be made to the Director, Meteorological Service, Lagos, from whom information sheets giving fuller details may be obtained.

## Owe Ile Yoruba

**Bi agbon ti nse, beni oyin nse wipe awon ko lo ta Oloko, Oju Oloko lo si wu kubo-kubo yi, Ajapa wa lo gbe orisa baba re jade, o wipe kabiyesi oba ki oyin ati agbon wa fi orisa Ogiyan bura wipe ko nse awon lo ta Oloko. Agbon ati Oyin seleri lati se be.**

# Lagos Executive Development Board

## Titun Ilu Eko Se

Lori Eto titun ti a ṣe, Igbimọ ti ṣe tan lati pese ile miran fun awọn ti a ti wo Ile Isowo wọn. Eyiyi je lori ile ti a ntun ṣe, ti ko si ni jẹ wipe a nduro de eto gbogbo. Anfani yi wa fun awọn to ni ile to ye koro ti ko si din ni ọdunrun opa ni igun mererin (300 sq yds.) ti oluwa rẹ si ti ni ile na fun igba ti ko din ni ogun ọdun.

Ki awọn ti akiyesi yi bawi ki wọn lọ ṣe iwadi ni ile iṣẹ wa nipa igba ti ao wo ibi iṣẹ wọn ati iru aye miran ti a o fi ropo fun wọn.

Lọna yi Igbimọ gba lati ṣe eto lati gba ile na ki wọn si san owo to to fun u. Lọna miran, iranlọwọ wa lati ya ni ni owo nibiti a gbe nfi owo ya ni labẹ eto yi.

**J. W. HENDERSON**
**Oga Ile Ise L.E.D.B**

December, 12, 1956.